## Asayan Oro

Ewurę wo alapata, bi ki o ku. Awodi wa igbin koto. Kini eiye oko yio fi Igbin se ? Ori l'o nise eda l'a yanmo.



# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI'L'EJO



## Akiyesi Pataki

A fiwe yi ş e ikede si awọn Aşoju iwe irohin Eleti-Ọfe kakiri agbaiye wipe, enikeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranşe si wa, a o pe lejo, ako si ni fi iwe irohin ranşe si enibe mo.



VOL. XI No. 640. LAGOS, SATURDAY, SEPTEMBER 12 — SEPTEMBER 18, 1959. KOBO MEJI (2d)


# Awolowo Lo Ki Jimo Ni Mosalasi Nla

EKO. Irọ ni tabi otitọ ni ? gbolohun kayefi yi ni o njade lẹnu ogunlọgọ awọn enia nilu Eko, paapa awọn alufa Musulumi ni ọjọ Jimo anọ yi Friday Sep 11, ni igbati wọn gburo wipe Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ pelu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ nlọ kirun Jimoh ni Mọsalaşi nla. Lati dede agogo mẹwa owurọ ni girigiri ti irun ti Ọlọla Awolọwọ nlọ ki yi ti nrọ kẹkẹ kakiri Opopo Victoria St, ati gbogbo awọn adugbo ti o wa ni agbegbe rẹ.

Bi awọn alalufa ti nmura pelu lawani wọn bẹni awọn Alhadji nşe itọju Mọkawiya wọn, awọn ẹlẹsin miran ewẹ, sọ wipe awọn yio lọ fun oju l'onjẹ. Ki a s i k o irun to sunmọ awọn Ọlọpa ti de agbegbe adugbo yi lati ri wipe awọn onijagidijagan ati awọn alakatakiti enia ko ri aiye lati ba eto yi jẹ.



OLOYE AWOLỌWỌ

A g b ọ w i p e Oloye Awolọwọ lọ fi ọpẹ fun Oluwa ni, o si tun lọ tọrọ adura fun ti ilọsiwaju ati alafia ilu yi ninu ọdun ti o mbọ.

Gbogbo awọn Saamọri Eko, Oloye pataki - pataki Ilu awọn alaşẹ Mọsalaşi ni o peju pesẹ ni J i m ọ to lọ yi.

## Omoba Oyekan Pe Ipade Egbe Demo

EKO. Iwonyi ni diẹ ninu ara awọn ọrọ ti Ọmọba Adeyinka Oyekan sọ ninu ipade ẹgbẹ Nigeria National Democratic Party ni gbangba isalẹgangan nilu Eko, ni ọjọ Saturday 4th oşu September 1959.

Awa ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ lo pe nyin wa si ipade yi nitori ki a ba le jijọ gbe ẹgbẹ naga soke, ki a ma si şe gbagbe işẹ ribiribi ti ologbe Herbert Makọli şe silẹ ki o to ku, o si yẹ ki a gbe iranti rẹ duro, ki a ma ba gbagbe ọkunrin na, Ejo nigboro.

Ẹjẹki nşe iranti meji kan ti o şe pataki ti ologbe Makọli şe ninu ẹgbẹ yi. Awọn ẹniti ọrọ na ba şoju rẹ, ko ni le gbagbe ologbe H. Makọli ninu ejọ ile Oloye Oluwa ni Apapa nilu Oyinbo ati ejọ ọba Eşugbayi Eleko nigba ti ijọba fi agbara wa kuro nilu Eko lọ si ode Ọyọ. Ọrọ ejọ mejeji nwọnyi şẹ nói jian.

Şugbon latigba ti ẹgbẹ Dẹmọ ti di alabaşe kanna pọ pelu ẹgbẹ N. C. N. C. ni ẹgbẹ Dẹmọ ti di ero ẹhin O yẹ ki ẹ gbaruku ti ẹgbẹ na lẹhin ki a le gbe irawọ rẹ dide. Mo ti mọ iru işẹ ti ẹgbẹ N. C. N. C. le şe.

Nigba pupọ ni awọn nkẹ ibosi orukọ mi nitori ki awọn ọmọ ẹhin mi ba le dide dibo fun won, gbogbo ileri ti nwon şe wipe awon le şu bi ojo ki nwon si ro, gbogbo rẹ ni nwon ti kuna.

Emi ko gbero wipe mo nlẹ gbadaawo lati gbẹ an iya ti nwon fi jẹ mi, bi o tilẹ jẹ pe, iya na po, idi rẹ ti emi şe fẹ lati da ẹgbẹ Demo temi silẹ ni ti wipe ero awon ẹgbẹ N.C.N.C. ko le duro şoju an, ileri ti nwon ba şe loni bi o ba di ọla yio yẹ.

Ni akoko kan, ni nwon pe ara won ni ijọba kan şoşo ero won ko nduro pẹ ki nwon to daru.

Ki ẹ foriji mi bi mo ba sọ ọrọ diẹ nipa ohun ti Olori ẹgbẹ N.C.N.C. fi şe mi. Lati ibẹrẹ ọdun 1949 si ọdun 1958 ẹgbẹ N.C.N.C. lo nran bi orun ti nwọn si ngbe mi gun aayan wipe ọmọ Dosumu lo yẹ ko jọba sinu Iga Idunganran, eyi lo mu ki awọn t o fẹran ile Dosumu tunbo gbaruku ti ẹgbẹ N.C.N.C.

Nigbati Dr Oloran-nimbẹ njijadu lati da ẹgbẹ Dẹmo tirẹ silẹ kuro ninu ẹgbẹ N.C.N.C., işẹ mi ni ko jeki o ni enia lẹhin eyi ni sababi ohun t i o ja Dokita na lọwọ ti ko fi n i ẹmọ ẹgbẹ, ti o fi ri gẹgẹbi o ti ri ioni.

Şugbon ere kini N.C.N.C. fi san pada fun mi, lẹhin ija tile ti awon tun kede Adeniji Adele Keji Olori ile Ado, gẹgẹbi Ọba Eko nigbangba. Ki okun le de mi mọlẹ, nwọn ti şe ofin ti ko ni jẹki nle ja fun ọba mọ. Ọrọ ọba ko tun wọ kotu mọ, paapa bi oba won titun na ba ni ohun ti o jẹ ti awon aşiwaju mi ti o ba wipe ti Ọba ni, ko si ani-ani, nibẹ nko tun gbodo bere mo.

Beni awọn ẹgbẹ N. C. N. C ti nwọn nşe irufe akọn wọnyi na ni nwọn tun kigbe wipe ẹgbẹ Action Group ati N. P. C. ti Oke Ọya ko fun awọn enia ni anfani alafia ni ipinlẹ wọn.

## ỌBA OWA JẸRI EJỌ APANIA NI KOTU

ILESHA Alaiyeluwa Ọwa, ọba Ilesha lo sọ fun adajọ ninu Kotu wipe ni a l ẹ ọjọ kan ninu oşu August, ni on ri ti ọkunrin kan de o si sọ fun on pe on ti pa awọn enia meji n abule Oşu, o si fi ada kan han on ti o jẹ eyiti o fi şişẹ buruku na.

Ọdaran na sọ wipe awọn obinrin mejeji ti on pa na ti gba ogalaadẹjẹ owo lọwọ on nitori ki on le fẹ ọmọ wọn obinrin şẹ nwọn ntan on jẹ ni. Ọmọbinrin ti o njẹ Awawu Abikẹ sọ fun awọn ọlọpa wipe, owo mi ni mo nwiro lọwọ, ki ọdaran na to ja wole ti o si fi ada ge on lọwọ sonu o si şa iya on ni aşapa. O si ti şa obinrin kan pa ti orukọ rẹ njẹ Ayọka Ayọku ni abule Osha.

Ẹjọ na koiti pari, ipade ejo na tun di igbamiran ki nwọn to ma ba ejọ na nşọ.


E Dibo Fun

Egbe

Afenitere

## ỌKUNRIN KAN FI PỌUN MẸTA GBA ETI

OSHOGBO. Ọdọmọkunrin kan ti o njẹ Raimi Akanji ni a gbọ wipe o gba ẹgbọn rẹ leti nitoripe eleyini jẹ ni gbese ṣile mẹjọ abọ, ti ko si ti ri owo na san pada.

Adajọ sọ wipe, iwọ gbo-ju-gbaiya, o siwọ lu Odi ẹyin, nitorina, ki o lọ san pọun meji abọ si kotu. Bi ko ba si ri san ki o lọ si ẹwọn oṣẹ meji, nitori oju ti o ya ti o fi lọ gba ẹgbọn rẹ leti.

Lẹhin na ki o lọ san pọun kan, sile mẹsan ati naira fun ẹgbọn rẹ na fun owo igbati kan ti o gba.

Lẹ na sọ pe ile ọkunrin ti a gba leti na nitoripe Raimi lọ ka mọ inu ile rẹ ni agbole Ọdẹfin nilu Oshogbo ni. Nigbẹhin ni Raimi ṣẹṣẹ wa nbebe. Ṣugbọn, ọpa ko ba oro mọ, igi ti da, ejẹ si ti fọ.

## ỌWỌ TẸ OLE TO JI AGOGO ỌWỌ

Ọyọ. Irohin kan wa wipe ọdọmọkunrin kan wọ ṣọbu ibiti nwọn nta agogo owọ o si ji won ni agogo ọrun ọwọ kan lọ. Ṣugbọn oru ba ibiti nu jade ki nwọn ma ba ki mọle fun ẹsun ole.

O wa lọ sapamọ sinu apoti ofifo kan, enikeni ko si mọ pe enia mbẹ ninu apoti na. Ili gbalẹgbalẹ ti nkọ ilẹ bọ wa inu apoti ti ọkunrin na sa pamọ si o ri nwọn da ilẹ idọti na si. Sibẹ ọkunrin na dake mọ ibẹ, ṣugbọn nigbati won tẹ ina bọ inu panti na ni ọkunrin na lọ ibosi ni awọn ọlọpa ba ki mọbẹ, nibi ti nwọn nyẹ ara rẹ wo ni nwọn ri agogo titun lọwọ rẹ.

Adajọ bere pe, iwọ gbajumọ! eyi ha tọ si ọ? O dahun pe agogo na wu mi pupọ, o si fi wọ mi lọju, mo fẹ fi si ọwọ nigbati emi pẹlu iyawo mi ba fẹ lọ si ode. Adajọ na sọ pe bi iwọ ko ba kuku niyawo, o san ju wipe ki o lọ jale lọ. Nitorina, ki o lọ si ẹwọn ọdun mẹta.

E MA KA
IWE IROHIN
ELETI-OFE
LOSOSE
O KUN FUN
IROHIN ALADUN

## OLUKO KAN SALAISI NI SOKOTO

ṢOKOTO. Malam Moyi Ṣokoto, ti o jẹ ọkan ninu awọn Aluia ti o nkọ ọmọ ni kewu, ni a gbọ wipe o ṣalaisi ninu ile rẹ ni Ṣokoto, oruko baba rẹ Malam Abubakar Maikutoru.

Oloogbe yi bẹrẹ kewu ni ile kewu ti Kadi ni Ṣokoto nigbati o pari kewu rẹ o lọ kọ ofin kewu nipa ẹsin Imale, lẹhin ti o yege ninu ẹkọ Kewu tan, o tun ṣiṣẹ olukọ nigboro Kano lati ọdun 1942 si ọdun 1945 ni akoko ogun.

Ojẹn lọ ṣe olukọ ni ile ẹkọ Ṣokoto Middle School lati ọdun 1945 si ọdun 1948 lati ibẹ ni Ijọba ilẹ Hausa ti gbe ga si ipo Alabojuto ile ẹkọ.

A ko mọ iye ọdun ori rẹ, a ko si gbọ wipe o binrin tabi o ni iyawo. Ọba ko gbe si ibẹlẹ rere.



CEKOP
EXPORTER OF PLANT EQUIPMENT AND COMPLETE WORKS
Warszawa — Poland, P.O. Box 112, Cables CEKOP WARSZAWA.

We supply complete equipment for :

— coal and ore mines
— coal and ore concentrating plants
— installations for hydraulic coal mining including hydro-monitors

We carry out :

— technical and economic studies
— hydrological and geological prospecting

We provide :

— technical building, assembly and operational documentation

Assembly works will be completed and plants put in operation by our specialists.

# Iya Oba Lo Be Ile Kenya Wo



**Lakoko ti iya oba Gẹsi lọ bẹ** apa ọna oke ilẹ Kẹnya wo, o de ilu kan ti awon npe ni Nakuru, ibẹ lo ti ri awon omobinrin ti a nwo ninu aworan yi eniti a gbe nko won bi a ti nṣe iṣẹ ile, o duro, o si nwo won.

# E Dibo Fun Egbe Atenifere




## IYAN MU NI OMU, OLO MỌ SỌ ỌMỌ RẸ NU.

Apa 3

Nigbati eyi o je agba gun ori igi lọ, o ri ina kan ni okere, ibẹ ni awon ọmọ na kori si, akoko na je onere-nere alẹ; awon ọmọ na kan ilẹkun. Iyalenu lo je fun iya ajẹ ti o ngbe inu ile na wipe, enikan laiya tun o wa kan lekun mọ on lori o dide kiau lọ si bi ilekun na.

Nigbati o yoju sode, ero yaa lati ri awon ọmọ were, o bere wipe, Iya yin ha da? Nwon ni awon ko ri. Baba nyin nkọ? Nwon ni awon ko ri. Iya ajẹ na wole lọ suu, anu awon ọmọde na si ṣe. O si ki won wole.

Teletele, iya ajẹ na ni awon ọmọ were meje gẹgẹbi iru awon egbon Akerele yi. Nigbati ile su iya ajẹ na te busun won si egbe awon ọmọ tire. O de fila fun awon ọmọ tire, ko si de nkankan fun Akerele ati awon egbon rẹ.

Nigbati o kuro lọdọ won tan Akerele dide, o si fila ti o mbẹ lori awon ọmọ iya ajẹ na, o fi awon ẹgbon tirẹ lori. Nigbati o di ọganjọ oru ti iya ajẹ na ko sinu ago rẹ anu si kuro, loju rẹ o si di ajẹ. O kun wo yara ibiti awon na gbe sun si, o ba le awon ọmọ tirẹ o si mu ẹjẹ won gbẹ.

Ki ilẹ to mọ, Akerele ti ji awon ẹgbon rẹ, awon gba ẹhinkule jade, nwon si salọ. Ki o to di wipe ilẹ mọ, nwon ti rin ja si oju ọna ti gbogbo enia mba lọ si ọja, ti awon ara ilu won naa, ki iya ajẹ na to ji loju orun. Nigbati o ji, o yara lọ lati ji awon ọmọ tire lati wa mu Koko gbona aro kutu-kutu. Nigbati iya ajẹ na wọ yara ibiti awon ọmọ rẹ wa, o ji won gẹgẹbi o ti ma nji won, ṣugbon ko gbọ esi.

Nigbẹhin lo to wa ri wipe awon ọmọ on ni on pa. O sare lọ wo ibiti Akerele ati awon ẹgbon rẹ sun si, ko ri won, lo ba binu fa ada yọ ti o si nlepa awon Akerele ati ẹgbon rẹ.

Nigbogbo akoko yi, Akerele ati awon ẹgbon re ti de iso baba won ni arin ọja. Ibẹ ni baba won ti de ọja ba won. O si mba won sọrọ kini nwon ti rin lọwọ, ni Iya ajẹ yi wọ ọja ti o si ada mọri ti o si nwa awon ọmo na kakiri.

Ariwo ta pe, Akerele so fun baba won pe, ki o wo Iya ajẹ ti o mbo wa pa won yi. Ni baba won ba fa kondo yọ, ti gbogbo awon ero ọja fa igi ati kumo yọ, ti won si lu iya ajẹ na pa, ti ọlomo si ko awon ọmọ rẹ rele.

Nisu ọsẹ na ni oba Olomu se ikede opo ọnjẹ, onjẹ wọ ilu, ọjọ ro, iṣu ati agbado ta, ayọ si de si gbogbo enia.

O pari.

ELETI - OFE

...IJUWỌN ỌKO ṢE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos. "ELETI - ỌFỌ LAGOS"
P. O. Box 468 Phone 23370

VOL. XI. NO. 640. SATURDAY SEPT. 12 - SEPT. 18, 1959

# Gbamu Ko Tan Iba.

Owe Oke wosika wa ọsẹ yi ni afi ṣe ẹṣin ọrọ aṣayan wa fun ẹnyin ọkawe wa gẹgẹbi nwọn ti ma nsọ wipe Owe ni ẹṣin ọrọ, bi ọrọ ba sọnu, owe ni afi nwa-bẹ gẹgẹ ni ọrọ na ri.

Ohun ti o fa sababi ti afi pa owe na ni ti iwa aifeni pe ẹni, aif'enia pen'a ti ara oko fi nsan bantẹ wọ'lu iwa ikorira enia ordẹrede miran paapa enia dudu ti o ti di ewu agbada ti awọn enia funfun tabi awọn Oyinbo apa ọna Ariwa ile Gusu (Northern Rhodesia) gbe wọ s'ọrun ti nwọn fi huwa si ẹni - ọla Sir Francis Ibiam ninu eyiti awọn ọmọ panti ọmọ koriko ti o mbẹ ni ilu na fi kọ lati ta ife omi gbigbona kan (Tea) fun u nitoripe awọ ara rẹ jẹ dudu.

Nigbati okiki iwa ẹranko na kan kakiri o jẹ ohun itiju fun Olotu ijọba ilẹ na lati gbọ wipe ẹniti ijọba Gẹsi yẹsi ti Alaiyeluwa Ọba ilu Gesi ṣe apọnle rẹ depo ti ọba na fi eye ola da lọla ni nwọn fi abuku kan bayi mu ki Olotu ijọba na yara tọrọ gafara ati idariji lọwọ ọlọla Sir Francis Ibiam fun iwa abuku na.

Loju tiwa itọrọ gafara tabi idariji ko to, bi ki o fi ileri kun wipe irufẹ iwa bẹ ko ni ṣe mọ nilẹ South Afrika, ki awọn enia funfun ti o mbẹ ni ilẹ na fi ọwọ sowọpọ pẹlu Olotu ijọba wọn, Sir Roy Wilensky pe aṣiṣe ni eyiti nwọn ṣe na irufẹ iwa bẹ ko ni ṣe mọ. Eyi l'o mu wa p'owe Oke wosika wa pe: "Gbamu ko ta ba"




## ẸJỌ OGUN DA ROCHA NI KOTU

EKO. Nipa iwe ẹbẹ ti awọn ọmọ Da Rocha meta ṣe, ti nwọn si fi ranṣẹ si adajọ agba wipe ki o jẹ ki aṣoju ti awọn ba yan lọ ṣe iṣiro owo baba won ti o mbẹ ninu Banki ati awọn dukia miran ti baba won ni.

Awon ti o ṣe iwe na ni Ọgbẹni Alexander Da Rocha ti o jẹ akọbi Ologbe Candido Da Rocha ati Angelina Fọlaṣade Thomas ati Louissa Turton.

Oloye Fani Kayọde sọ fun adajọ wipe, on ko fi ara mọ iru iwe ẹbẹ ti awon eni na ṣe, nitoripe Ologbe Da Rocha ati yan Bayọ Doherty ni Babansinku ki o to ku, awon mejeji nwonyi lo si ni ẹtọ lati ni mimọ nipa iye owo ti o mbẹ ni Banki ati iye dukia ti o ni.

Ibẹ ni Adajọ ti ro ọrọ na siwaju sehin, lo ba fa iwe ẹbẹ na ya, o wipe ogun ti o ba ti ni Babansinku, ẹlomiran ko gbọdọ ba du u.






# EBUN ILERA



Ara-lile, agbara ati okun-inu ni işura ti o kọja idiyele, awọn ẹbun ẹda ti o dara julọ ni. Ko si onjẹ miran ti o nfun ni l'okun-ilera atata bi Ovaltine, ohun ti a l'i peelo rẹ ni onjẹ atẹjẹşe ati eyi ti o nfun ara ni okun. Mimu Ovaltine lojojumọ ni ọna to dara julọ ti o si rọrun julọ lati fun ni ni ọpọlọpọ ilera ti o dara tẹlẹ, lati ri i daju pe a ni okun lojojumọ ati idẹra, orun asunwọra. Egbẹgbẹrun awọn ọlọmọde ni nwọn mọ anfani atata ti Ovaltine ni, onjẹ olomi ti o dara julọ.





## ỌKUNRIN KAN ŞA ỌRẸ RẸ PA

LỌKOJA. Ọkunrin kan şe ikede fun awọn enia meje ninu awọn ọrẹ rẹ wipe, on fẹ şe sara ọjọ ibi ki nwọn wa ba on şe ajọyọ na. Nigbati ọjọ pe o fun wọn ni onje ati ohun mimu, nwọn jẹ, wọn mu, nwọn si yo ragbadu.

Nigbati ọkunrin na roye pe nwọn ti yo, io ba fa ada yọ, o si şa ọkan ni aşapa. Eyi ni ẹjọ ti awọn ọlọpa ro niwaju adajọ.

Awọn ọlọpa sọ pe, ọkunrin apania na jẹwọ wipe, nitotọ ni on şa ọkunrin na pa, idi rẹ ti on fi şebẹ ni pe, ọrẹ on ni tẹlẹ, şugbọn, o gbẹhin lọ gba iyawo on. Ati pe, on ti fẹ lati pa ologbe na ti pẹ şugbọn on ko ri aye, nitorina ni o şe pe wipe ki o wa jẹun nile on ki on le ri aye f'ọwọba.

Ọdaran na sọ fun adajọ wipe, nitotọ ni on pa ọkunrin na, şugbọn on ko mọ igbati on şişẹ na nitori on ti mu ọti yo, awọn ọlọpa şi nwadi nipa ọrọ.

## AWỌN ỌMỌ DA ROCHA KO FẸ ŞE ẸJỌ MỌ

Awọn loya tọtun - tosi awọn ẹlẹjọ ninu ogun Ologbe Candido Da Rocha, ti lọrọ mọ Ọlọrun l'ọkan, lati jumọ fiye denu sọ wipe awọn yio lo pari oro won nile, ki nwọn mu ẹjọ kuro ni kotu.

Ohun ti awon mba ara won rojo le lori ni wipe Baba won fi owo repẹte silẹ fun awon bi ogun, a si gbo pe owo na ti o mbẹ ninu Banki to okẹ mẹdogbon poun.

Awon Loya na fi oke le wipe bi awon ẹlojo ko ba tete pari ẹjo na nile ki o to to ojo Jimo ti o mbo ,awon yio tun ko s'ẹnu ẹjo na.

Nigbati awon ka iwe ihaogun na fun wọn Alexander Da Rocha, Iya afin Ẹbun Turton ati Omidan Folasade Thomas taku wipe awon ko gba pẹgẹbi awon ti şe iwe ogun na, ni awon fi gba Lọya Lambo ati Loya Moore.

Dokita Oladele Da Rocha, ti o je pe on lo ni pupo ninu ogun na gba Lọya Kayode, Somolu, ati Şowemimọ.

Ninu iwe ogun na Dr. Ladele Da Rocha ati Bayo Doherty ni Ologbe Candido Da Rocha funra re yan lati jẹ Babansinku lori ogun ti o fi silẹ. Bi a ba ti fun gbọ iyoku oro na si ọọ ma gbo.

## Awolowo Gbe Ire De Fun Awon Osise

Eyi ję okan ninu awon ileri ti Oloye Awolowo se fun Egbe awon osise bi o ba wole, ninu idibo ti o mbo yi :—

Ogunlogo ni awon osise ti a npe ni onise ojumo ti o nsise fun wakati merinlelogoji losose. Bakanna ni awon akowe ti nwon ko nsise lojo Sunday sibe nwon o gbowo re, ojo isinmi (Holiday) nwon gbowo re, sugbon awon osise ojojumo nwonyi ni opomulero ilu, nitori laisi ti w o n ilu ko ni dun.

Niwon igbati nwon lagbara lati sise, o y ę k i nwon ma gba owo, b i amodi ba si de, o y ę ki nwon rowo gba pelu, bi nwon b a s i dagba d i arugbo o yę ki nwon ma ri owo gba.

Iru eyi ni Oloye Awolowo ro, ti o fi wipe, bawo ni eniti o fi gbogbo aiye re sin ilu re ti o wa di igbati ko le sise mo ti o wa fe owo ku ?. Bi on Awolowo ba wole ni Eko fun ijoba apapose, gbogbo awon osise ti o ba ti se odun meji lenu ise ni yio di eniti a ko ni daduro mo.

## Alufa Osipitan D'ologbe

Gbuke ni a gbo irohin iku Alufa Eniowo, E.G. Osipitan ti o je alufa fun ile isin Saint James nilu Iperu. O salaisi ni ile alaisan ti University College ni Ibadan. A gbo pe odun ori re je metadiladorin.

A b i Alufa y i nilu Ijebu Ala ni odun 1892, o ko eko ati ojulowo ede Yoruba n i ile e k o Saint Andrew ni Oyo.

Lehinna lo lo gba oye Alufa ni Melville Hall nilu Ibadan. O m o meje n i Ologbe y i f i silę ati obinrin kan. Nilu A l a lagbegbe Ijebu O d e ni nwon gbe sinku alufa na ni ojo Sunday t i o koja 6th osu September, 1959.

## ODOMOBINRIN LO JI ILEKE

GUSAU. Odomobinrin kan, omo ogun odun ti oruko re nje Yaro Kacho ni awon yandoko rami ti nwon si gbe duro niwaju Alkali ilu Gusau wipe o ji ileke ati ohun oso ara bi ologota poun.

Sugbon odomobinrin na dahun pe, nwon puro mo on ni on ko jebi esun na ni Alkali b yę ejo na si ojo Monday 14th osu Sep. 1959.

## ADAMODI DOKITA WEWON

IBADAN. Okunrin kan, ti o nje Adetunde ti ko kose isegun ri, ti o wa lo gbe abere ti o si ogun apa fun won kakiri, o pe ara re ni Dokita, o si ngbowo lowo won, alalikura ko mo ise isegun rara.

O wa lo gun apa fun omode kekere kan, omo lewe ni abule kan ti nwon npe Abule Akinlagun ni agbegbe ile Ife, depo ti ome na fi ni lati ku.

Adajo agba ri wipe ejo Dokita na jebi, boya omo na ko n i ku, bi ko ba si abere ti nwon gun fun ni, nitorina ki adamodi Dokita na yara lo si ewon odun mejo pelu ise asegan.


**E MA KA**

IWE IROHIN

**ELETI-OFE**

LOSOSE

O KUN FUN

IROHIN ALADUN





**Learn at Home to be a Private Home Nurse . . .**

*AND SO BE ABLE TO HELP YOUR OWN PEOPLE WHEN THEY ARE SICK*

You can learn Home Nursing and practical Medicine in your spare time, by correspondence, in easy lessons. Whether you are a man or a woman, this home training will be very valuable to you. You not only learn how to look after your own family, but can also get a well-paid part-time or full-time job as a private-duty St. Vincent Home Nurse.
The St Vincent Course, in Section 1, gives you general instructions in nursing: how to record pulse, temperature, respiration; how to give exercises, massage, health baths, diets; the care of a pregnant woman and nursing a baby.
In Section 2, you learn about what medicines to use in the treatment of nursing of various sicknesses. How to deal with infections and children's diseases. Emergency treatment for burns, bites, food-poisoning, etc. Modern methods of birth control. How to calculate the arrival of a baby. Important medicines in everyday use. How to build up a career. Nursing is a noble occupation — your people need more Home Nurses. Fill in this coupon and post it NOW.

Please send me, without cost or obligation, full information about your course, and your Enrolment Form.

**St. Vincent**
CORRESPONDENCE COLLEGE
P.O. Box 7927, Johannesburg

NAME ..................
ADDRESS ..................
TOWN ..................
Age .......... Sex .......... Occupation ..........
Your standard of education ..................

E-O/12/9/59


## AFI ENIA SOLE O KO NI L'ERU LO

Okunrin kan ti o ję dereba ti o nwa moto loya fi omose r e so ile nigbati o fe jade. Iyalenu lo je fun dereba nigbati o pada ti ko ba gbogbo eru re mo.

O lo rohin fun awon olopa, nwon si ti bere si se ode omose re na kiri ki owo won to lo te ni ilu Akure.

O jewo pe nitoto ni on ko eru na, o si wa ni ikawo on: awon olopa siro awon eru ti o ko l o na je poun mejidiladota. Adajo si wipe, o fi igbesi aiye re ta rafulu, o ni ki o lo si ewon osu mesan pelu ise asekara.

## DUKE OKO OBA MBO WA SILE GHANA

Accra. Oba obinrin ilu Gesi ni a ti gbo lakoko kan wipe, o mbo wa be ile Ghana wo ni inu odun yi, sugbon abewo na ko tun bo si mo.

Sugbon Dokita Kwame Nkruma ti ri iwe gba lati odo ijoba Gesi wipe, nisisinyi oba Obinrin ti feraku, ko le rin irin ajo lo si ona jijin mo, sugbon lati fi han bi inu on ti dun t o nipa ati wa be ile Ghana wo, bi o ba di ninu osu November odun ti awa yi, on yio ran oko on "Duke of Edinburgh" lati wa soju fun on.

## OWO TE OLE TOJI OWO KOTU IBILE

Omokunrin kan ti o nje Ganiyu ti o nse iranse fun K o t u ibile ti o nmu iwe lo kakiri, lo lo se apamopamo owo kotu b i poun merin ki owo olopa to tee.

Adajo ni ki o lo san poun marundiiogota fun poun merin ti o ji, bi ko ba si ri owo na san, ki o lo si ewon osu mefa.

Agbo wipe Ganiyu gbajumo o si je eni ti o feran fari gidigidi Sugbon o fi poun merin ba omo luwabi re je.


**Kere o !**

A ni orisirisi ogun German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO

**BROTHERS**

MEDICINE STORES

7 Egerton Road Lagos

# Baba Ko Omo Re Sile

IWAYA. Omokunrin kekere kan ti ko ju ọmọ ọdun marun lọ ni a gbọ wipe, baba rẹ fi sọjọ sinu ile kan, lati mu ọjọ May 1959, ti o si ba tirẹ lọ ti ko boju wo ẹhin mọ. Awọn olutọju awọn ọmọ asunta sọ wipe, ninu osu May ni ọkunrin kan mu ọmọ rẹ ti o njẹ Bayọ de ilu Iwaya. A gbọ pe baba omo na jẹ ọkan ninu awon Woli aladura. Baba omo na dagba to ẹni ogbon odun, o si jẹ enia kukuru, aladura si ni pelu. Oniwasu ni aladura na ti o nti ibikan de ibi keji.




## NWỌN ṢA BALE ILE KAN NI ADA.

KALABA. Lọjọ Atalata ti o kọja lọ yi niwọn agogo mẹta abọ oru ọganjọ, ni ọkunrin Kalaba kan fi igbe ta, ti gbogbo enia si rọ giri wa gba sile. Ṣugbọn alajori ohun ti ọkunrin na ṣe ki eyi to de si, ko ye enia.

Oruko ọkunrin na ni Esien Udo ara ilu Ibiobio, o je okan ninu awon ti o nla igi patako, o si tun jẹ okan pataki ninu awon gbajumo ti o ni adugbo kan ti nwọn npe ni Ishe Street ni ilẹ Kalaba, on ni nwon sa ni ada yana-yana.

Ọpọlọpọ awon aladugbo ti o tete sare de ibẹ, nwon ba sa ni ajana. Sugbọn nipa iranlowo awon aladugbo na, ọrọ to mejinini awon ti o wa yẹ ni hura ko yi nwon si yara gbe ogbeni na lọ fun itọju ninu ile Alaisan.

## Awolowo So Baba Oro Fun Egbe Alakuko

Ẹkọ Ọlọfẹ eyiti Ọlọla Oloye Obafemi Awolowo da silẹ ni ilẹ Nigeria, gbogbo aiye lo asala re, ti nwọn si nje igbadun ẹbun ẹkọ ọlọfẹ na.

Ẹsia eta eni kii ga bi o ti wu ki o niyi ki o lọla to, taja tẹrao lo njẹ igbadun ẹbun ẹkọ ọlọfẹ na. Bi Olomi ti nje ninu rẹ, bẹni Alakuko nje, Demọ nje, Kiriyo nje bẹni Imale nje pẹlu.

Bi enia ko ba nṣe alaimọre enia, ohun ti gbogbo enia nje ti nwọn nṣe adura fun Awolowo, ni awon okunrin ẹgbẹkẹgbẹ kan wa bẹrẹ si fi run pako wipe: Ilewe ọfẹ ti Oloye na da silẹ ko ṣe rere kan. Ẹnikan Oke ọhun, o ni, o nro gun ni ẹṣin rẹ s'ẹsẹ.

Awolowo da won lohun wipe, ẹniti ko ba ninu didun si ile iwe ọfẹ ti oo da silẹ, ẹ jẹki eluwarẹ yọ ọmọ rẹ jade kuro ninu ilewe na.

## OBINRIN NA TUN PADA KU.

Obinrin kan ti a ti ṣerohin re wipe nigbati nwon le gbe sinu yinyin lo kapa soke, ti nwon si ti ibẹ gbe lọ sinu ile iwosan.

A gbọ irohin wipe, sibẹ-sibẹ obinrin na ko ni aiye lati fi se mọ, ki ile ọjọ keji to mọ, o tun jowo ẹmi rẹ sile.

Nisisiyi, oku na mbẹ ninu yinyin. Tabi ẹ ko taiye.

## Baba Agba Rora Jo



SIR WINSTON CHURCHILL.

Ọmọde, Olose nla Alagba Winston Churchill ti o ti jẹ Olotu Ijọba ilu Gẹẹsi lasiko Ogun ajakaiye keji, ti o si ti d'agba di ẹniti o jẹ ọdun mẹrinlelọgọrin (84) ni a gbọ wipe awọn ẹgbẹ oṣelu Conservative Party ti opo Ijọba mbẹ lọwọ won tun yan sode fun ibo ti nwọn yio di ninu oṣu October 1959 ti o mbọ yi.

Ki a maṣe gbagbe wipe, Sir Winston Churchill, baba alagba yi, ni ojo ogbo ori rẹ mu fi aye silẹ fun Sir Anthony Eden lati di ipo Olotu Ijọba mọ, ki ailera ara to tun mu eleyini na j'awasilẹ fun Ọgbeni Macmillan ti o mbẹ lori ipo na nisisiyi.

Orin ti a ro lati kọ si yiyan ti nwọn tun yan baba agba yi s'ode ni a:

"Baba agba rora jo.
Ara d'ara agba o".

## Isile Ise Iwe Irohin

ALKORAN MIMO FUN OLOTU IJOBA APAPOSE

ENO. Alhaji Tafawa Balewa, Olotu Ijọba Apapọṣe ni ilẹ Nigeria ti a nwo ninu aworan yi ni a gbọ wipe awọn Oyinbo a te iwe irohin kan fi Alukorani kan ta lọrẹ lẹhin ti o ba wọn ṣi ile itẹwe won tuntun tan.

. Ọrọ na lọ bayi, gẹgẹbi irohin ti a gbọ lẹnu onirohin Eleti—Ọfẹ ti o lọ si ibi iṣile na ni ọjọ Alamisi. A gbọ pe ọgan ti Alhaji Balewa ti de bẹ ni Oyinbo ogunra-gbongbo ibi ile iṣẹ itẹwe na, ti o gun ọkọ ofurufu wa lati ilu Oyinbo ti orukọ rẹ nje Cecil H. King, ti d'de lati gba tọwọ-tẹsẹ Ọgbeni King ni n wọn ọdun die ti awon bẹrẹ si te iwe irohin awọn ko ju igba ọmọ ibilẹ Niger a lọ ti awọn gba siṣẹ ṣugbọn nisisiyi ti ẹrọ iki ti bo awọn ogunlogọ ọmọ ilu yi ti o wa nibi iṣẹ na ti wọn nṣe anfani.

Iwe Alukurani ti a fi ta Alhaji Tafawa Balewa lọrẹ yi ni a gbọ wipe iru rẹ ṣọwọn nitoripe eyiti wọn ti kọ ogba atijọ ni



TAFAWA BALEWA





PHILIPS

'West African' RECORDS

Wholesale Distributors:

Badejo Stores, 5 Ologogun St., Lagos
Dayo Development Co., 161 Victoria St., Lagos
Jony Ola Fajumolu & Bros., 21 Balogun St. West, Lagos
Nwoss Bros. Stores, 24 Asa Rd., Aba
Ebele Egbunam Stores, 38 Church Road, Kano
Olasinboh Business Enterprise, P.O. Box 53, Kano
Ezenweaku Trading Stores, 48 Aggrey Road, Port Harcourt

PHILIPS (W.A.) LTD. P.M.B 2023 Lagos



M.B.T.
(MAGIC BLOOD TONIC)



Iná dé, òkùnkùn paradà. M.B.T dé, òkùnrùn fò lọ. Ẹ̀jẹ̀ dúdú cáré, òyì pọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀. Àlá búburú wọ'gbó, àìlèsùn f'ẹhìn-ẹ̀kùn. M.B.T. Ìrògùn-ẹ̀jẹ̀ tí nmú ni jẹun b'íkàn, amú ni yàgbẹ́ bí ọ̀kùn, amú ni lọ̀ bí àkèrè. Abiwẹ́rẹ́ f'ẹ́boyún, agbẹ̀jẹ̀ dì fawọn abiyamọ. ... àti àìyà-j'íjá ko si rẹ́nití nlo o.
4/6d pẹ̀lú 1/6d owó-ọkọ̀.

ARADAN STORES P.O.Box 2 EBUTE-METTA.


Printed & Published by The Union Printing And Publishing Company 28, Kosoko Street, P.O. Box 47 Lagos, Phone 23570